# IWE SI OLOTU

## Ilu Imushin Nfẹ Ile-Iwosan Nla

Olotu, inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ninu iwe nyin oloyinmọmọ lati kesi awọn alaṣe Ijọba Ibilẹ Ijẹbu Imushin ati paapajulọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati fun Ijẹbu Imushin ni ile iwosan nla ti awọn alaisan orişirişi yio ti ma a gba ogun.

Ilu Imushin ki işe ilu kekere rara ni agbegbe Ijẹbu ati pe ile iwosan na yio wulo fun awọn enia to wa ni agbegbe ilu na ati papa fun awọn ọmọ ile ẹkọ giga to wa ninu ilu na ati agbegbe rẹ.

Eyi papa si jẹ ohun to nbọ si wahala fun ọpọlọpọ awọn enia lati lọ si ile iwosan to tobi fun itọju ara wọn.

Inu awọn enia ilu na yio dun bi Ijọba rere na ba le şe awọn nkan‿na fun wa ati pe ọpọlọpọ awọn nkan miran lo n/e ilu na ati agbegbe rẹ niya.

Awọn nkan na ni ile ifi iwe ranşẹ to tobi ati ina ẹlentiriki fun ilu Imushin ati agbegbe rẹ. A nreti nyin bayi.

Mo dupẹ o Olọtu, ajinde ara yio ma jẹ o.

Emi ni,
Anthony Abayọ,
Ijẹbu-Imusnin.

## Ẹ Ye Fi Iwo-Ẹran Ja

A dupẹ pupọ fun Ọlọrun Ọba oloore Ọfẹ O jẹ ki ọke-aimọye wa yika igun mẹrẹrin aiye şe Ọdun-Ileya l'ayọ.

Mo fi iwe ọpẹ mi yi kewọ lati be awọn obi lọkunrin, l'obinrin. Ẹ şe ikilọ fun awọn Ọmọ nyin pe, ki nwọn maşe şe ere-egeti mọ ki nwọn maşe fi awọn Iwo-ẹran Ọdun-Ileya ja mọ ki işe ohun ire Ohun eşu ni.

Awọn Ọmọde ti nwọn feran lati maa fi iwo ja, ma a nşeşi fi lu ara won l'ọrun-ọwọ tabi lẹşẹ, nigba-miran.

Ki Ọlọrun ma fi ijamba şe wa o, Afẹwọfa ko dara, Ohun eşu ni o J., Enyin Ọmọde, ẹmaşe şe afọwọfa o. Ẹni ri o ba ni eti, ki o gbọ o.

Emi ni
Alhadji Y. A. Disu
EKO.

## Iwa Yi Nfẹ Amojuto

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati kesi awọn Ọlọpa lati ba awa enia ti ma nwọ mọto ni Mushin ati Agege fun iru iwa ti awọn awa mọto ti nlọ si awon ilu na nhu.

Iru awon iwa ti awọn awa moto na nhu ni ki nwọn ma ko ero to iye to yẹ ki nwon ko ati pe awon oni moto na ma nsare pupọ ju,

Inu awa enia to ma nlo si awon ọna na yio dun bi awon Ọlọpa ba le ba wa şe amojuto awon janduku awa mọto na.

Awọn oni moto na ko bikita rara fun gbogbo ọna ti ko dara ti awọn oni mọto ki rọra wa mọ to na ninu rẹ.

Eyi to si tun buru pupọ ju ni bi awọn oni moto na ba ti de ọna Agege lọhun nwọn a fẹrẹ ni ki awọn eru ma gun le ara wọn ori dipo ti mọto nwọn ki o ko ero ti o ni lati ma ko nwọn asi ko ero ju bẹ lọ.

Inu wa dun bi awon Ọlopa ba le mu oju to eyi

Mo dupẹ o Olotu
Emi ni
John Omisandi
MUSHIN

## Nfẹ Iwe Irohin Imọlẹ

Olotu, inu mi yio dun bi ẹ ba le jẹ ki iwe nyin oloyinmọmọ Irohin Imọlẹ tete ma de ọwọ wa ni Akurẹ ati pe eyi ti ati ri iwe na ka ni Akurẹ ati agbegbe rẹ ti pẹ pupọ.

Inu wa yio dun pupọ bi ẹ ba le ran wa lọwọ bi iwe nyin oloyinmọmọ yio şe tete ma a de ọdọ wa ati pe a si fẹ ki iwe na pọju gẹgẹ bi o şe pọ to lati ẹhin wa lọ nisisiyi, nitoripe, angba dun iwe na.

Iwe nyin oloyinmọmọ na si lun wa ni itan to dara ati pe ọpọlọpọ itan awọn ilu ni a si ma nri ka ninu iwe na ati papajulọ ọro lati ẹnu Yẹyẹnatu oni yẹyẹ Eko.,

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni şa nyin lẹşẹ o

Emi ni
Adeọla Adekọla
AKURẸ

## Nibo ni owo Ijẹbu ti nwa?

Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye lati fi ibere mi yi siwaju awon ojogbọn ti nwọn nka iwe Irohin Imọlẹ

Ni igba ẹbogbo'ni mo maa ngbọ'ti mo si nfi oju mi ri awọn owo kan ti nwọn npe ni owo Ijẹbu " (Counterfeit) Awọn o‿o wọnyi jẹ owo ti ko dara,

Nibo ni awọn owo wọn yi ti uwa? Njẹ awọn Ijẹbu lo nşe owo na bi? To ba jẹ bẹ kini şe ti awọn Ijọba wa ko şe mura lati ri wipe iru owo bẹ ko waiye mọ?

Ọlọrun ko ni jẹ ki agba tan lori ilẹ aiye. Ejọwọ ẹşe alaye ọrọ na fun wa,

Olotu, ajinde ara yio ma jẹ o.

Emi ni
Gabriel Ọla
Eko

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹta eşu karun (3/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Akọwe Agba

## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Pupọ ninu awọn egbogi rọbirọbi ti wọn npolowo ti wọn si nta kakiri igoroun Eko ati ni igbereko ko ni şe iwsan wọn lailai afi ki o ri ojulowo hauhhaun atamasc egbogi ti o la-bara gidigidi ti o le şe iwosan rẹ tim de inu ifun ati igb-aya ti yio mu ọ ma tu "Ikọ" mọ bi kẹlẹbẹ jade ti o ba nhu ẹ titi yio fi tan ni inu rẹ qatabata. Awọn ikọ miran wa ti o dabi ẹnipe wọn ama la ogun lati orişirişi egbogi tabi ti o ba jẹ pe beni, agba ọ ni imọran wipe ki o ma lo egbogi awon ara ilu Abyssinia ti nwọn npe ni "Etibard" pẹlu egbogi ti o ba amu

PORAL TABLETS
THIOLYPTINE SYRUP
THYMO-EPHDRIN LINITUSS
ETIBARD ABYSSINIA POWDER

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ gbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbe tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna-ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma nje ki nia ru nipa wahala tabi aikomi le sun daradara lọsana ati loru-gbiyanu lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara idigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi şorokiti ti wọn nta kakiri

O daju ubẹ iwọ yio bere si ri alafia, iwọ yio ma‿şun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yen

Bere egbogi ajẹbina yi ni şọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8 Plamchurch Street, Lagos
Phone:-22878 ,Nigeria, (Ọja ita Faji)

## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Ti Nbọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ KI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ŞINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa jọwọ şe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubor gbogbo ẹda patapata" Amin

### "WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ọyẹ ki o ri na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6, £3 fun dosinl*

MANAGER

Mansfield 4 Millwall 1 Montrose 2 St.anrae

Ẹ ... Ikọ ... Imọlẹ

# "Nwọn Pe ẹ lọmọ Igi"

Lati Ọwọ Alhjai Y, A, Disu

"Nwọn pe ẹ lọmọ igi, o nhuwa ọmọ igi,
Nwọn pe ẹ lọmọ aṣa, o nhuwa ọmọ aṣa,
Nwọn pe ẹ lọmọ ẹran, o nhuwa ọmọ ẹran."

Ohun yi ti ṣẹlẹ si ile aiye lọjọ ti o ti pẹ pupọ. Ọpọlọpọ awọn ọmọ ilẹ Yoruba ati ọpọlọpọ awọn ara ati ọmọ Ẹkọ ni nwọn si fẹran lati ma a kọ orin aladun yi lẹhin ti nwọn ba ti jẹ ti nwọn si ti mu tan. Ni ibi ere ayọ tabi ere aṣeyẹ ni nwọn ma a nsaba kọ orin aladun na,

Mo ṣe akiyesi pe o wa ninu ọkẹ aimoye ẹnyin onkawe, gbajumọ Irohin Imọlẹ ti o ti gbọ orin yi ri tabi ti o fẹran lati ma a ba wọn kọ o gbadun orin na pupọ ṣugbọn njẹ ẹ mọ ohnn ti o faa ti nwọn fi nkọrin na?

Gbinrin ki sa jẹ Kumolu lai ni idi ko si si ohun ti o ṣẹlẹ laini idi ki Ọlọrun jẹ ki ohun ire tabi ohun ti o dara ti o si ni anfani ninu, ma a ṣẹ'ẹ si wa titi lailai o

Ki Ọlọrun maṣe jẹki oju wa ri ibi . Ki O si gbe wa leke awọn oninububuru oloribuburu, alakọri ati awọn kẹnimani o "Amin". Ẹ jọwọ, ẹ ba mi ṣe Amin tọkan-tọkan.

Lasiko kan, ọkunrin kan mbẹ. o dudu, o gun pupọ. aguntaṣọlo ni i kẹnimani ni i, ọpurọ ni i. o le ṣe ẹrẹ kẹ-eebu pupọ, ogbole ni i, o si mọ ẹgbọn ati ete ti o ma a fi ntọrọ nkan lọwọ ẹniti o ba ni laari l'ọmọde l'agba kaakiri adugbo ati yika ilu.

A si ma a ṣe'agbe rẹ na lọdọ ọkuurin ati obinrin bakanna A ma a sọ pe "O ko fun mi l'obi ọjọ Aiku (ọsẹ) O ko fun mi l'obi ọjọ Ẹti (ọjọ Jimọ) Ọrẹ mi, inu yi nfẹ ọ akara (burẹdẹ). Inu mi nfẹ bọta

A si ma a fi ọwọ ku ikun rẹ. Ọgbẹni na ya ara ju adiẹ elepipi lọ,

Ko ni iti loju rara Oni ijamba enia si ni Ibi rẹ ko pe Ni idi baba nikan ni nwọn bi i re,

Ẹni ti o ba si nfun un ni nkan, a ma a kan sara si i Ẹni ti ko ba fun un, yio si ma a sọ ni orişirişi orukọ.

Bẹẹni Ọlọṣa ni Ọgbẹni na Ọgbẹni na ni nwọn kọkọ ko o sin na fun ni ọjọ kau ti ojo rọ fẹẹrẹfẹẹrẹ.

Ni ọjọ keji ti o lọ ṣe aṣemaṣe kan lọdọ baba Ọlọrọ kan ti o nta iwo ni nwon tun kọ orin,

Bi a jẹyi tan
A o jẹmi si
Ajẹ jẹ tun jẹ
Bi a ba jeyi tan
A o jẹ mi si
Ajẹjẹ tun jẹ
Abọ re o,

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20-Fec 18) O jẹ ohun ti o ma nwu ọ lati parọ nkan, bi o ba fẹ ṣe bẹ eyi ni akoko na ti o dara lati ṣe. Ire ni yio ja si fun ọ loni.

PISCES (Feb 19 Mar 20) Oni li ọjọ ti o dara lati pari edeaiyede kan ti o ti nda ọ lamu, iwọ yio si ba wọn ṣe apejọ titun kan loni nibẹ ni iwọ o ti ri aye sọrọ ẹdun ọkan rẹ jade·

ARIES (Mar 21-April 19) O tọ ki o fi si ero nipa ọrọ awọn ẹbi rẹ iwọ yio ri pe, gbogbo awọn ọrẹ ati ojulumọ rẹ lo ṣe tan lati ran ọ lọwọ loni.

TAURUS (April 20-May 20) Ọjọ oni ko dara lati yanju ọrọ, nwọn o si pari ija larin iwọ ati ọmọbinrin kan lọjọrọ ti oni bi nwọn ba da ọ lẹbi, maṣe kọ.

GEMINI (May 21-June 20) Ṣe suru pupọ loni ohun gbogbo yio si yori si rere, nwon o pari ọrọ owo kan larin iwọ pẹlu ẹnikan ohun gbogbo yio si ma yọri fun ọ si rere.

CANCER (June 21-July 20) Sọ asọye ọrọ rẹ ki o han ketekete ki osi yanju ọpọ enia lo nfẹ ṣe iranlọwọ fun ọ. Bi o ba ngbero lati lọ si ajo ọjọ oni dara lati gbera.

LEO July 23 Aug 22) Ninu ohun kohun ti o ba nṣe ranti ki o maṣe gbagbe nipa iṣẹ rẹ Maṣe owu nipa obinrin kan maṣe ba ẹnikẹni ja ṣugbọn ma gba imọran ọrẹ

VIRGO (Aug 23-Sep22) Gbogbo ọrọ rẹ yio bẹrẹ si yanju nipa obinrin Iwọ yio ni owo lọwọ jaburata irira ati itẹlọrun yio wa fun o Iwọ yio lọ si ipade kan loni.

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Iwọ yio ṣorire loni, owo yio si ba ọ jẹ gbogbo ohun kohun ti nwon ba fi lọ ọ jẹki o jẹ gbigba. Iwọ yio lọ sipade atata kan loni awọn obinrin yio ma so mọọ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ohun kan yio mi ọ lọ kan, nipa irẹwẹsi okan, mase sahun si ẹni kan, obinrin rere ni iwo yio ba sọrọ loni, ti ẹba ṣe adehun, maṣe yẹ adehun na.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Ọrọ kan yio ṣẹlẹ ni sisọ, yio si pari daradara, Ayipada yio han lọdọ obinrin ti o ti mba sọrọ ri, iwọ yio si ri ohun kan gba laira tẹlẹ loni, [illegible]


BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*



## Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn obinrin ti ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ekọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugbi Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn. ẹfọr abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ ọpo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti owa-ofun didun, [illegible] orişirişi omura [illegible]

